# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 869 SATURDAY MAY 18 — 24 KỌBỌ MEJI (2D) 1963

Aiyetilujara:

## Oyinbo Ayorunbo Kan Ti Orun Ke Si Awon Araiye Nibi Ipade Ajo Won

ADDIS ABABA—A ye ti lu jara! Oyinbo ọmọ Amẹrika kan ti e njẹ Gordon Cooper ti ara ilu rẹ ran lọ si oka sanma ni ijẹta lati wa ọgbọn wa fun araiye kan saare si awọn iko orilẹ ede Afirica nibiti nwọn gbe nṣe ipade ajọ ni ilu Addis Ababa ni Ethiopia ni ana.

Ni oru ijẹta ni awọn ọjọgbọn ara Amẹrika fi ẹrọ alagbara kan ju Ọgbẹni Cooper si sanmọ wipe ti o ba rin jinna soke tan, ki o ma wa yi gbogbo agbaiye kiri ni ẹmejilelogun.

Ki e to to akoko ti nwọn ju ọkunrin na si sanma ni dokita onişegun ilu Amẹrika ti ntọju rẹ lati wọ bi o ba ni agbara to lati ṣe iṣẹ kole-kole na ti nwọn fẹ yan si, nwọn si mbọ ọ bi ẹran ti a fẹ pa jẹ.

Gbara ti nwọn ti ran ọkunrin na lọ si "ỌRUN" ni awọn ọjọgbọn wọnyi ti gbe jingi awo, ẹrọ igbohun ati awọn nkan orisirisi nkan miran ti enia le fi mọ nkan ti o nlọ ninu afẹfẹ soju ati seti. Gbogbo bi ọkunrin na ti nyi aiye kakiri ni o nfi ẹrọ-gbohungbohun ti nwọn di mọ lara sọrọ si ilẹ.

Nigbati o di ẹkẹrindinlogun ti o ti nyi aiye ka ni o bẹrẹsi ke si awọn ikọ ti o pejọ ipade nla ti nwọn nṣe ni Addis Ababa nisisiyi

O ni "Ẹ ku ... nibẹun! emi Gordon Cooper, ayọrunbọ lo nki yin. Ọgọrun mali (100 miles) ni mo fi jinna ni oke sanma nibiti mo gb... wa si yin nisisiyi. Emi na ṣẹṣẹ kọja firi lọdọ yin nibiti ẹ gbe nṣe ipade ni Addis Ababa nisisiyi ni. Mo ki yin. ajọtu ẹg ẹ o, ipade yin a yọri si rere o."

Ọkunrin ayọrunbọ na ti bọ sile nisisiyi, o wa ku ki o rohin nkan ti o ba bọ oke "ỌRUN" fun awọn alakoso ti o raan lọ.

### Ọlọpa Mu Akowe Ti O Na Padi Lọna Sosi

ABẸOKUTA—Ọwọ awọn ọlọpa ti tẹ akọwe kan ti nwọn ni o na alufa Oyinbo Padi kan ni Ibara lọjọ ọsẹ nigbati o nlọ ṣe adura fun awọn Ijọ rẹ. Rev. Father Hanniffy ni orukọ Padi ti ọdaran na na.

Edmund Iroajanma ni orukọ ti awọn ọlọpa pe ọdaran na nigbati nwọn wọ wa siwaju adajọ-agba ni kotu Isabọ ni ijẹta pe ki o wa dahun ẹsun rẹ.

Ẹsun ti awọn ọlọpa ... ọdaran na lọrun ni pe ni ọjọ ọsẹ ti o kọja yi, o lọ dena de Alufa Padi Hanniffy nigpati Alufa Padi na nlọ ṣe adura-agadi fun awọn Ijọ ati awọn ọmọ ile ẹkọ ti Padi na nkọ ni ile ẹkọ giga ti nwọn npe ni St. Leo's Collge ni Ibara.

Awọn ọlọpa ni lọdọ Padi yi ni ọdaran yi ti nṣe iṣẹ oṣu ti o si san ponun mẹjọ mẹjọ fun un loṣoṣu ṣugbọn nwọn jọ ṣẹ gbolohun asọ kan pẹlu Oyinbo Padi yi ki o to lọ dena de loju ọna, o si na Oyinbo Padi na ni a na bolẹ.

Nigbati nwọn ka ẹsun rẹ fun un, o ni on ko jẹbi, awọn ọlọpa si ti sun ọjọ ẹjọ rẹ na si waju.

ERIN KAWỌ IJA LORI !

### Ijoba Gesi Mu Enahoro Kuro Nilu Won

LONDON—Arẹ npe ọ, o nda'fa ni ọrọ Oloye Anthony Enahoro, igbakeji olori ẹgbẹ oṣelu Afẹnifẹre (AG) ti ilẹ Nigeria, ti awọn ọlọpa ilẹ na ti nwa kiri lati bi ọdun kan lati wa dahun ẹsun wipe o wa ninu awọn kan ti o ditẹ gbigbona lati bi Ijọba Apapọṣe subu, ti o wa ṣe isansa wa si ilu Oyinbo nibi. Awọn Ọlọpa ti waa gunlẹ ni Eko ni ana lati wa jẹ ẹjọ ẹsun ti uwọn ti nwa a fun na.

Onirohin wa ... ni on gbọ wipe ni ọtun ... ọjọ Aje ni awọn ọlọpa ... wọ Oloye Enahoro na ... Ade... ọ Kotu-nla ... npe ni Lan... l'Eko.

O di oṣu meje gbako ... nisisiyi ti Oloye Enahoro na ti gunlẹ si ilu Gẹsi ti nwọn npe ni London; orukọ olorukọ ni o fi sinu iwe-aṣẹ (passport) ti o lọ fi wọ ilu na.

Tẹlẹtẹlẹ awọn ọlọpa ilu Nigeria ni Ghana ni ilu awọn Aganyin ni awọn ti ngbọ wipe o lọ sa pamọ si. Awọn alakoso Ijọba Nigeria si fi igba kan kesi awọn alakoso Ijọba Ghana na wipe ki nwọn fi Enahoro ranṣẹ si awọn nitoripe awọn fe ba ro ẹjọ ọtẹ ti on pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ dẹ si Ijọba Nigeria ki o to fi'lu silẹ.

(Wo yoku loju ewe keji)

Eyi Ara !

### Oku Obinrin Kan Jinde Ni Idoma Ninu Posi

IDOMA—Oku adiẹ ko ẹriti o kun ... ni oro oku Obinrin kan ti o jinde ninu posi nigbati nwọn fẹ sin in ni Abule Awuke ni Ipinlẹ Ariwa ni ọjọ Aje (Monday) ti o koja ẹni ogoji ọdun ni obinrin na ti orukọ rẹ nje Inyamu Ctokpa.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ayorunbọ obinrin na, inu ni ... sọ wipe o nrun on, ki o to ku lọjọ keji, awọn ẹbi rẹ si wẹ ẹ, nwọn kan posi ti nwọn gbe oku rẹ na si.

Nigbati awọn gbe posi ... de itẹ nibiti nwọn gbe fẹ sin in si, ọkan ninu awọn ti ... posi na ni nkankan nmi posi na, ki awọn ṣi, ki awọn yẹ inu rẹ wo. Nigbati nwọn ṣi posi na, ... nwọn ri obinrin ti o ti ku na, ti o la oju, ti o nrẹrin.

Gbogbo awọn ara abulẹ na si ti nlọ wo ni ọd... kọ rẹ

# Eleti-Ofe D'araba

...oju ewe kinni)

... alakoso Ijọba ... kọ jalẹ lati fi ...ahoro ranṣẹ si ... Nwọn fi ọrọ ... nwọn fi lọgbọn. ...ba Apapọṣe ilẹ ... ofin ni awọn ...re ọgbẹni isan-...ọ wọn.

... alakoso Ijọba ...a si tun kọwe si ... Nigeria lati ala-...eran ẹgbọnrin ti ...wọn njẹ lọbẹ ... awọn ti tun ofin ... o pa wọn pọ ...wọn ara Nigeria ṣe ...gbara ti awọn ti ...i gba omi nira ni ...a

... pọ lẹhin eleyi ni ... Enahoro paapa wa ...ra rẹ lọ si ilu Oyin-... ri on nlọ se eto ... awọn ọmọ on meji ...wa ni ilu na. Gbara ... ce ilu na ni ọwọ ...a Oyinbo ọlọpa tẹẹ.

Lati igba na ni nwọn ... Bẹrẹsi ṣe rogbodiyan ... wipe awọn ni lati daa ...da si Eko ki o lọ jẹ ẹjọ ... ti awọn ọlọpa fẹ ...a ro. Ẹnahoro kọ lati ...padi sile, o ni on fẹ sa di ...sia Ọba Gẹsi nitoripe ofi... wa fun iru ẹniti nwọn ba ...wa fun iru ẹsun bayi pe o ... ie sa si abẹ Ijọba Gẹsi fun abo.

## Akowe Ile Owo Gbe wa Odun Marun

AKURẸ—Adajọ Kotu ga...ran nibi ju akọwe ile-owo kan ti nwọn npe ni Nathaniel Ogunṣeyẹ, ẹni ọgbọn ọdun sẹwọn ọdun marun fun owo ti o ji gbe ni National Bank ti ... ti nṣe iṣẹ. Gbogbo owo ... awọn ọlọpa na ni o ji gbe jẹ ẹgbẹ... ponun o le mẹrin ... wọn ...ia mej. ... si ile-... o nigbakan si ni owo

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)




The load is heavy, the ground difficult, the engine is working at full power and yet the driver has perfect control. The light Mercedes-Benz re-circulating ball steering is precise to a fraction of an inch. Exact manoeuvering, safe use of marginal space, absolute track steadiness and excellent lock are features of this steering which is just one of the many advantages that all Mercedes-Benz trucks and buses have in common.

**Precision to a fraction of an inch**



MERCEDES-BENZ

Available at:

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB) IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT H... ...OURT: ABA

Sub—Distributors:

**ARMELSTRANSPORT LTD**

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

### Awon Iwe Asiko:

# Amoju Ni Yio Ba Ekun Sare Je

Ninu Iwe ALUFA ATILADE

## Ise Agbe

Ni igba lailai, ọkunrin kan wa ti a Sare. Sare jẹ Yoruba, o si ngbe ọkan nin ilu nla ti ilẹ Yoruba.

Bi o tilẹ jẹ pe Sare ngbe ilu nla, iṣẹ agbẹ ni o nṣe. Iṣẹ yi ni lati ma mu u gbe oko ni ọpọlọpọ oṣu larin ọdun. Ẹkọkan bi akoko Egun ọdun tabi Igba Oro ni on i ma wa ile.

Ni akoko Sare,ṣ igbo pọ nilẹ Yoruba awọn ẹranko ti o roro bi ẹkun, kiniun ati amọtẹkun ama ṣe enia ni jamba li ọna oko, papa julọ nigbati ebi ba npa awọn ẹranko wọnyi.

## Lati Owo AKOWE

Ni ọsan gangan ijọ kan, Sare w a ninu eko rẹ. Bi o ti gbe ori soke nibiti o gbe nroko ni o ri ẹkun ti mbọ tara si ọdọ rẹ.

## Kukute

Sare fẹ lati salọ, ṣugbọn ko si aye fun u lati ṣe bẹ. Ori Sare wu, o to agbe. Nigbati Sare ko mọ eyiti yio ṣe mọ ki o fi le bọ lọwọ ẹranko buburu yi, o fi ara mọ ẹgbẹ igi kukute kan ti o wa ninu oko rẹ.

Ẹkun yi de ẹba ọdọ rẹ. O duro si. O gbe imu s'oke o gborun afẹfẹ. Sare mọ pe ẹkun yi kẹfin on. Ẹru tun ba Sare si i, ṣugbọn o fi ara balẹ patapata ko mi ara rara. Nigbati ẹranko yi wo ẹgbẹ ọtun ati ẹgbẹ osi ko ri ẹnikan, o la oko na kọja o si wọ inu igbo lọ.

Nigbati Sare rii pe ẹranko yi ti kọja lọ ati pe ko si pada s'ẹhin mọ, Sare kuro ni idi kukute, ko mu ọkọ rẹ, ko mu ada rẹ, ile li o kọ ori si.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Irohin Kakiri Agbaiye ...

### NWỌN KO SỌJA LỌ SI ALABAMA

BIRMINGHAM, Ala.—Ni oru ijarun ni ijọngbọn tuntun tun bẹ silẹ larin awọn Oyinbo alawọ funfun ilu Amẹrika ati awọn enia dudu ibẹ, lẹhinti nwọn ti pari rogbodiyan gba were, ngko gba were ti iwa inunibini ti nwọn si awọn alawọ dudu ilu na.

Ni aṣalẹ ọjọ ọsẹ (Sunday) ti o kọja, a gbọ irohin wipe awọn alawọfunfun kan fi ọkan boju wọn, nwọn wo tuto ayọkẹlẹ dudu kan ... sare ni isakusa gba ... ti Dokita Martin Luther King tiṣe olori awọn enia dudu na gbe ngbe, nwọn si ju bọmbu mẹrin sibẹ awọn bọmbu na ṣe ọpọlọpọ enia ni ijamba, nwọn si tun ba ile jẹ.

Lẹhin eyi, awọn Oyinbo alawọ funfun na tun ṣe ọgbọn, nwọn yinbon sinu Ṣọṣi Baptist kan nibiri awọn enia uudu na gbe nṣe ẹsin lọwọ.

Nigbati alamojut Ijọba ilẹ Amẹrika, Ọgbẹni Kennedy, gbọ iru rogbodiyan buruku ti o tun bọ silẹ larin awọn enia-dudu ati awọn enia dudu yi, o paṣẹ wipe ki nwọn osi ọpọlọpọ awọn ṣọja lọ k eti ilu Birmingham ni Alabama.

Nwọn si wa ni ẹnu rogbodiyan na lọwọ lọwọ yi

### Oselu Nja Ni Kenya

Ni ilu Nairobi, Kenya, awọn ẹgbẹ oṣelu enia dudu ti nwọn wa nibẹ ti bẹrẹsi ba ara wọn ja ijagboro nibiti nwọn gbe ti nṣe ikede idibo ti nwọn fẹ di ni aipẹ yi.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan f'aya kaya pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Jomo Kenyatta ti nwọn npe ni KANU nibiti nwọu upolowo idibo, nwọn si lu ara wọu bole; awọn enia ti o farapa le ni ogun enia, ti awọn ọlọpa si ru wọn lọ si ile awọn alaisan. O el ul igbaa enia ti owo awọn ọlọpa na tẹ ti uwọn ko lọ si itimọle.

### Aje Metta Gba Ojo'Ku

A gbọ irohin wipe adajọ ilu Tanganyika kan ni ki nwọn lọ pa awọu ọmọbinrin mẹta kun ti nwọn ṣẹṣẹ wọ ẹgbẹ awọn AJẸ ilu na, ati pe ni oju wọn ni nwọn Je pa obinrin kan ti o njẹ Fatima Nyaugudai ninu Igbo lọjọ kan.

Bi adajọ yi ti da ẹjọ na tan, ni ọkan ninu wọn ti o kere ju lọgun gbẹ ẹ, ti o gbara ṣanlẹ, oi kiuni on kan yi.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE

KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọ́n, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-títàn ati lati mã fi yáná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

# ELETI–OFE

A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI–ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 869 SATURDAY MAY 18 MAY 24 1963


Oro Olotu:

## Owo Riba Ko Dara (2)

Alufa Sọrọ, ojo ku, o ni Ọlọrun gbọ ọrọ on. Ninu iwe "Eleti–Ọfẹ" ti a tẹ jade n un ọsẹ ti o kọja, ẹnyin ọkawe wa ri ka ninu ọrọ Olotu wa ti o fẹnu ba ọrọ RIBA JIJẸ ti o d aṣọ, da ṣokoto fun awọn ọpọlọpọ akọwe Ijọba ati awọn ọlọpa wa tobẹgẹ ti ọpọlọpọ wọn ko jẹ ṣe iṣẹ wọn ni ọna ti o tọ ati ọna ti o yẹ mọ, a fi ti a ba fi owo riba bọ wọn lọwọ.

### Abuku Nla

Gẹrẹ ti ọrọ olotu wa yi jade ni awọn oniwe irohin kan ti nwọn npe ni SUNDAY TELEGRAPH ni ilu Oyinbo ni ijeje ninu rẹ ni nwọn si fi ẹnu ẹtẹ kan ọrọ awọn Minisita alamojuto iṣẹ Ijọba ilẹ wa. Nwọn ni OWO RIBA JIJẸ ni nwọn fi nsanra lọtun losi.

Abuku nla oniyọrọ na pọ tobẹgẹ ti nwọn fi sọ wipe ọrọ riba jijẹ na ni o nle gbogbo awọn Oyinbo ajoji olowo ti nwọn ti jẹ da iṣẹ silẹ pẹlu owo nla nilẹ wa sa; nwọn ni ẹru iwa awọn minisita alamojuto iṣẹ Ijọba wa mba awọn olowo ilu Oyinbo lẹru.

Ọna mọkanlelọgbọn ni nwọn fi ṣe alaye nkan ti ko jẹ ki awọn Oyinbo olowo yi ko wọn wọ ilu fun wa mọ. Ninu awọn ọna mọkanlelọgbọn na ni ki a bu owo gọbọyi le ile ati lẹ ti a fẹ fi haya fun awọn Oyinbo oniṣẹ nwọnyi, ki a ma tete fun wọn ni iwe-aṣẹ ọba lati mu nkan owo-ṣiṣe wọ'lu nitori ki awọn enia wa ba le ri owo–ẹhin gba l'agba gbadun.

### Arun Oju Ni..

Awa oniwe irohin Eleti–Ọfẹ ko le sọ bi irọ ni irohin yi bi otitọ ni ṣugbọn ARUN OJU NI . . Tani yio sọ wipe on ko ri ọda owo bi o ti nda wa to ni ilẹ yi nisisiyi? Ọrọ na kiṣe ti awọn onisowo arin ilu nikan; bi ọda owo ti da awọn oniṣowo nile ni o da awọn agbẹ loko

Ko si nkan ti o fa eleyi ju iwa ọkanjuwa ati anikanjọpọn lọ. Iwa ki-enia-mo-ni yi lo fa bi o ko fun mi ni owo-ẹhin ngko ni ṣe ẹtọ fun ọ lẹnu iṣẹ ti o bẹ mi

Ọrọ na wa di ipakọ oni pakọ ni a nri. ẹni ẹlẹni ni o nri tiwa. Awọn Oyinbo oniwe irohin ti o dabi ẹni wipe nwọn fi abuku yi kan awọn Minisita alamojuto iṣẹ Ijọba wa ti ri wa tan ki nwọn to yọ lu wa.

Iyoku dọwọ wa lọmọde ati lagbalagba. Gbogbo wa ni a wa ri nisisiyi pe oju gbogbo araiye ni o nwo wa.

## Alagba E Ku Abo!

O jẹ aṣa ilẹ awa ọmọ Yoruba lati ma ki ẹnikẹni ti a ba ni ifẹ rẹ lọkan nigbakugba ti o ba ti irin ajo de, yala o lọ si oko ni tabi o lọ si odo lati pọn omin ni. Ẹniti awa oniwe irohin -Eleti-Ọfẹ fẹ fi ọrọ E KU ABỌ ti ẹsẹ yi ki ni Gomin a agba wa, Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe, ti o ṣẹṣẹ ti irin ajo de lati Ipinle Iwọ Orun Nigeria.

Lati ọjọ ti Gomina-agba na ti f'Ekò silẹ, ti o nlọ si irin-ajo ni awọn Eleti-Ọfẹ ti mbọ lọ, ti a si ṣe akiyesi iyi ati ẹyẹ ti nwọn nṣe fun un ni gbogbo ibiti o nde. On alara paapa mọ wipe ko si nkan ti o ti o dabi irẹpọ ti gbogbo wa jake jado ilẹ Nigeria nilo gbe lojojumọ.

Bi ko ba si irẹpọ larin awọn ara ilu aya ilu ko le ba'lẹ rara bi o ti wu ki a sọ wipe ominira wa dara to. Ki a jọ ko ọmọ lu bọ, ki nṣe awọn nkan temi ni nkan tirẹ, ni a npe ni irẹpọ, ko nṣe ki a ma ya nkan olukaluku si ọtọtọ.

Boya ni eyiti Gomina-agba Ọlọla wa ti irin-ajo yi de a le sọ fun awọn ti nwọn nsọ wipe ki olukuluku da igba iya rẹ gbe (North for Northerners, East for Easterners and West for Westerners) pe aiye ko lọ bẹ. Nṣe ni a jọ rin pọ ti yẹ ni

Alagba, ẹku abọ !

## Iwe Si Olotu

### E TUN REDIO SE . . .

Ẹ gba mi laye lati bu Awọn elerọ Asọ o redio sọrọ lori ẹrọ spoti redio wọn ti o ma nkuu nigba ojo nigba gbogbo, a si ma ṣe hẹlẹ hẹlẹ, ọrọ rẹ ni ko ni yọ jade dede. Nigba miran a ko ni gbọ nkankan ti o nwi lati owurọ de alẹ.

A ngbadun ẹrọ redio na pupọ nitotina, a bẹ wọn, ki ni o-tete ma ba wa tun awọn nea dio na ṣe ni asiko ki w le ma mọ bi nkan ti nlọ si ni aiye.

Bi o tilẹ jẹ wipe owo ti a nsan loṣu ko pọ, owo ni owo njẹ.

Mo dupẹ Olotu fun aye ti ẹ gba mi iwaju ni ẹ o ma lọ fun wa.

Emi ni,
Tawa Kalitu Shekoni,
Ita Alagba,
Eko.

### KILO NJE IYALE ?

Olotu, ẹ jọwọ mo fẹ ki awọ ọkawe yin ti o ba mọ itumọ aṣa awọn ọmọ Yoruba yi ko ti ye mi kinni idi rẹ ti a fi ma npe aya ti ọkunrin ba kọkọ ni ni IYALE, eyi ti o ba tun ni tele IYAWO ?

Ibere Keji : kini ṣe ti awọn obinrin ile ko ebodọ pe awọn ọmọ'le ni oruko ti iya ati baba ba sọ wọn ?

Ẹniti o ba bere ọrọ ni ofẹ idi rẹ gbọ. Ẹjọ ọ ki ẹ la ọrọ na ye wa.

Emi ni
Omidan Funkẹ A.
YABA

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Ole Gbe Kakaki

Ẹnyin ọkawe mi mo tun gbe temi de ni ọsẹ yi, mo gbọ wipe awọn ọlọsa kan wọ Afin Ọba ni Ake ni Abeokuta, awọn si fọ ile, awọn si ko nkan ọṣọ Ọba Alake Ademola Keji fi silẹ fun ẹnikẹni ti o ba tun fẹ gun ori-ite Ọba l'Ake lọ. eyi kamama!

Ọrọ awọn ọlọṣa na jẹki nniran ọrọ amoye kan ti nya mi agba, AJ LE OGUN ọmọ OGUN—MASO, feran lati ma so ngbati aiye re; o ni "ekun ku a fọwọ ba a." Nitotọ ni ọrọ yi, emi ko gbọ wipe awọn ọlọṣa lọ ile Ọba kan ni Abẹokuta ilu Ẹgba ri ambọn-ori Afin Alake.

Mo gbọ wipe awọn ADE—GOLU mẹta kan pataki wa ninu awọn ẹru ọba Alake ti awọn ọlọṣa wonyi kọ! Mo mọ awọn ADE—GOLU na daradara o si jẹki nniran itan kan nipa ọkan ninu awọn ade oba na,

### Alake Gba Fosi

Itan na niyi: o di ọdun mejdinlogoji nisisiyi ologbe Ọba Ademọla Keji yi ti ra ọkan ninu awọn ade ọba na, nwọn ṣe e fun ngbati ọmọ ọba ilu Oyinbo ti nwọn npe ni Prince of Wales mbọ wa yẹ ile yi wo ni April 1925; ade—ọba na ni o de lọ si Ibadan lọjọ ti awọn ọba ilẹ Yoruba lọ pade ọmọ Ilu Oyinbo nibiti nwọn gbe ti ṣe ẹyẹ Ẹ KU ABỌ fun un.

Ẹyẹ ti ade golu na pọ tobẹ ti awọn sanmari igba na fi kọrin bayi:

"Alake gba fọọsi, (first)
Lọwọ Alafin Ọyọ;
Ẹwu ilẹkẹ t'ọba wa wọ yi
O dara toto
Ade ori rẹ golu ni nwọn fi se.

Nitoto Ọba Alake tayọ (o gba fọọsi) lọwọ gbogbo awọn Ọba ti nwọn wa pade ọmọ-ọba ilu oyinbo lọjọ na lọhun. Bi o ti pade Prince of Wales tan ni Ibadan, ni o ti tun sare wa si Abẹokuta lati wa gba elejo ni nu ile tirẹ.

### Fatosin

Boya lati ọjọ yi ni ade-ọba yi ti wọ awọn wọnyi loju. emi Ayiluka ko le sọ, sugbọn mo mọ nkankan daju, iyẹn ni pe ole ti o gbe kakaki nibo ni yio ti fun?

Mo ṣe akiyesi ni Abẹokuta ti mo lọ ni aipẹ wi wipe awọn baba wa afọbajẹ ti nmura lati yan Ọba Alake tu tun miran. Nwọn ti fi oruko awọn ọmọ-ọba kan ranṣẹ si awọn BABALAWO wipe ki nwọn d'Ifa si orukọ wọn, ki a le mọ eyiti aiye rẹ yio rọ wa lọrun lehin ọla ni ilu Ẹgba, ki a ba le di i mu ṣinṣin

IFA TO SIN, nitotọ ko si ẹniti ko mọ wipe Odu Ifa ni nwọn nfi yan Ọba ni ile Yoruba. a fi igbati aiye daru, ti owo riba-jijẹ ko jẹ ki a ṣe eto mọ.

Iyoku di ọsẹ ti nbọ, o tun ma gburo emi Ayiluka si nipa ọrọ ilu Abẹokuta. Ifa a fọre o !




wọ ba nwa asiki funra rẹ bi?
Ki yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ
atigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npẹ nibẹ si ẹni yio ma lesi. Lọ bẹre nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

"BI IWỌ BA NWÁ ASIKI FUNRA RẸ"

Barclays tẹ se ọpọlọpọ aworan idaraiya to si wunni lati ma wò ninu sinima, eyiti iwọ papa ti lè ri tẹlẹ. Aworan yi jẹ itan nipa ọdọmọkunrin kan ti baba rẹ ran jade lati lọ wá ọrọ funra rẹ. Bi o ti nlọ lo pade enia mẹta: Ọkan ninu wọn ni mọto nla ti a



fi nko ẹro, ekeji jẹ arugbo, ẹkẹta jẹ onisowo to l'ọrọ. Awọn wọnyi ti nfi gbogbo owo wọn pamọ lọdọ Barclays, wọn si ti lowo pupọ. Wọn dá imọran fun wipe ki o lọ si Barclays Bank lati bẹre ifiwopamọ nibẹ.
Gbogbo awọn to wà ninu mọto



pẹlu rẹ si ṣe alaye bi owo rẹ yio ni àbo to, ninu banki, na yio ri bi a ti npa owo na mọ ninu apoti enirin ile to tobi. Ki o si mọ wipe nigbakugba ti o ba nfẹ owo na yio ba nibẹ. Iwọ na gbọdọ bẹrẹ si f'owo pamọ bẹ gẹgẹ.

BARCLAYS BANK D.C.O.

# Irohin Kakiri Agbaiye

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

## Ijoba Ilu Syria Tuka Patapata

Lati ọjọ mẹta ni Ọgbẹni Sami Jundi, ti nwọn fẹ fi jẹ Olotu Ijọba ilẹ Syria ti nsare sare, sare sodo lori ọrọ awọn oṣelu ilu na, ti ko ti ba ara wọn mu. Ninu Ọgbẹni Jundi na nṣe wahala lati fori ọrọ ija na tii si bikan ni gbogbo awọn minisita alamojuto eto iṣẹ Ijọta fi iwe ranṣẹ si wipe awọn ko ṣe iṣẹ fun Ijọba ilu na mọ.

Irohin kan ti a gbọ nipa ọrọ na ni wipe ọpọlọpọ awọn ara ilu ni nwọn ni awọn ko faramọ idapọ ti awọn alakoso awọn fẹ da awọn pọ pẹlu ilu Egypt. Nwọn ni awọn ko fẹ ba Nasser ṣe nkankan pọ rara.

Ijangbọn bẹrẹ ni ilu Damascus ati ilu ti nwọn npe ni Alepo; gbogbo awọn ara ilu na ni nwọn kawọ leri, ti nwọn nwọde kiri wipe awọn ko ba Nasser ṣe nkan pọ.

Awọn ṣọja ilu na ti nfi ibọn yanju ọrọ na fun wọn, nwọn si ni ki nwọn ti Ọgbẹni Salah Bitar, ti o ti fi gba kan ṣe olotu ilu na imole. Nwọn ti mu mẹta ninu awọn minisita atijọ ọmọlẹhinrẹ.

## Ewon Gbere Fun Dia Olotu Ilu Senegal

DAKAR—Adajọ Kotu giga ilu awọn Senega da ẹjọ ẹwọn gbere dọjọ iku fun Ọgbẹni Mamadou Dia, Olotu ilu Senegal atijọ, ti awọn ọlọpa ilu na ni o ditẹ si Ijọba pẹlu awọn mẹrin ninu awọn minisita rẹ atijọ, awọn Ibrahim Sarr, V. Ndiaye, Joseph Mbaye ati M. Alioune.

Ẹwọn ogun ọdun ni nwọn fi ẹnikọkan awọn minisita yi si, a fi Aliounẹ ti adajọ ni ẹdun marun ni ki o ṣe ninu ahamọ tirẹ.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi nwọn sun ni wipe nigba kan, Ọgbẹni Mamadou Dia lọ ba awọn sọja ilu na wipe ki nwọn di gbogbo awọn kọ lọwọ iṣẹ wọn ni ile igbimọ ti nwọn ba nsọrọ kan ti o di koko lọwọ ninu ile igbimọ ilu na.

Awọn oṣelu ilu Senegal ni awọn ko ni sọ Dia si ọgba ẹwọn, ninu ile kan ti awọn ara ilu ko ni le ma tete ri i ni awọn yio ju u si fun gbogbo ọjọ ti o ku laiye ti yio le.

# Awon Iwe Asiko

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

## B'ori

Bi Sare ti nyọ si ilu ni awọn enia mbii lere pe- Ẹru rẹ da? Sare bẹrẹ si da wọn lohun pe, "Ẹkun ni o le mi l'oko. Nigbati o de ile, gbogbo awọn enia rẹ, ẹbi re, aya rẹ, awọn aladugbo, ọrẹ atiọjọjulumọ ba a damọran pe o yẹ ki Sare bọ ori rẹ, eyiti o yọ ọ, ti ko jẹki ẹkun pa a jẹ ninu oko.

(iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

NKRUMAH NLỌ TILE TITE:

## NWON KO AWON ONIBARA KURO NI ILU ETHIOPIA

ADDIS ABABA — Ni irọlẹ ijarun ni awọn ikọ ilẹ wa ti o nlọ ba wọn ṣe ipade gbogbo awọn orilẹede Afirika ni Ethiopia wọkọ kuro nilu, Ọgbẹni Jaja Wachuku tiṣe Minisita alamojuto nkan okere ni o ṣe aṣaju wọn lọ. Awọn Olotu iwe irohin mẹrin ni o tẹle Ọgberi Wachuku lọ lati Eko.

Ni ọtunla Monday ni Ọlọla Tafawa Balewa yio wọ ọkọ ofurufu ni Ikẹja pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ lọ si ibi ipade na, awọn enia mẹrin ni o nmu lọ ninu awọn Minisita rẹ.

A gbọ irohin lati ilu Ghana wipe ọgọrun enia, awọn amugbalẹhin, ni Olotu ilu Ghana, Dokita Nkrumah nko lọ si ibi ipade na; nkan ti o fa eyi ko ye wa si rara, sugbọn a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ alatako ti nwọn sa kuro nilu fun Dokita Nkrumah paapa ti tẹ wa- ya sii wipe iwa a nko "ogun" lọ si ibi ipade gbogbogboo yi ko dara rara.

Ọgbẹni Kojo Botsio, tiṣe Minisita alamojuto nkan okere, ti ṣaju Olotu ilu na lọ, o si ti gunlẹ sibi.

Ki gbogbo awọn alejo nwọnyi to de ni awọn alamojuto Ijọba Ethiopia ti bẹrẹsi tun gbogbo oju ọna ilu wọn ṣe; awọn ko gbogbo awọn onibara ilu wọn atiị awọn arọ-enia kuro nilu lọ si ẹhin-odi, nwọn si ta asia orişirişi lati fi ki awọn ikọ kabọ.

# Awon Jomi Joke Oyinbo

Aworan yi ni igbati okunrin jomi-joke Oyinbo Gesi kan ti nwon npe ni Simon Paterson (on ni o nra koro ni akokan ninu aworan yi) luwe ninu odo ti nwon npe ni English Channel, ti o wa larin ilu awon Faranse ati Gesi, koja si ebute Dover. Awon jomi-joke egbe re yoku ni nwon duro ti i yi. Ojo kan ati abo ni o fi we odo na ja.



# Nigerian Lady Praised For Doctoral Dissertation In U S A

CHICAGO, ILLINOIS, — Grace Alele of Warri, Nigeria, has earned her Doctor of Philosophy degree at the University of Chicago and plans to return home soon to help train teachers.

Her dissertation on "The Dynamics of Educatiou in the Birth of a New Nation: Case Study of Nigeria" was described as a "most interesting and informative assessment of the social factors influencing the development of education in Nigeria"

This description came from Professor C. Arnold Anderson, one of her teachers in the Education Department at the Uniuersity of Chicago. He is Director of the Comparative Education Center there.

Professor Anderson said Miss Alele's study "throw considerable light upon the key role that educated men have played in the emergence of the Nigeria nation."

Miss Alele's attended elementary school in her hometown and went to Queens College in Lagos for her secondary education. She earned two degrees at tee University of Ibadan. and from 1954 to 1957 she taught mathematics at Queens School in Ede.

She came to the United States in 1957 as a graduate assistant in the Mathematics Department at the Univers ty of Vermont earning a Master degree in 1959.

She next entered University of Chicago and was awarded her doctoral degree recently at the University's 301st convocation.

President Geoge Wells Beadle, in ceremonies at Rockefeller Memorial Chapel, handed Miss Alele her diploma and bid her "welcome to the community of scholars."

## 650 Chinese Refuse To Go Home

DELIH (ISI)—According to the Hindustan Times as many as 650 Chinese now intorned at the Delhi Camp in Rajasthan, have refused to return to Ghina.

They are believed to have told camp authorities that even as internees they were enjoying a freer life in India than they could hope far if repatriated to China.

The 650 opters for India include about 8 internees who had could earlier wanted to return to China but have since revised their option on similar grounds.

They are likely to be allowed to return to their places of residence and business and resume their normal avocations.

The Dehli camp had about 2000 Chinese internees who were rounded up from different places in the Eastern border to region North Bengal and Assam in the wake of the Chinese invasion in October. Those persons were considered security risks and kept under surveillance under the Foreigners act.

Government later told the internees that they could return to China if the desired it.

## Ports Authority Men In Britain For Studies

LONDON—Eighteen mangerial trainees from Nigeria have joined a full-time residential course in management organised in London in respose to a request from the Nigerian Ports Authority.

The course, which lasts 10 weeks, is eing held at Hendon College of Technology under the surpervision of the Colleg's Department of Management Studies. The Nigerian Ports Authority has sponsored 13 of the students of the course, the Shell Company of Nigeria three and Electricity Corporation of Nigeria a further two.

The students sponsored by the N.P.A. are: M. A Abba; M A Aminu; J O Anda; I U Ihegborew; B Jimeta; M S Katu; R Long-John; S Mohammed; B E Offiong; Z D Ohiani; J O Owotade; M Suleiman and S Wushishi.

These sponsored by Shell are: B O Bamgbose; E E Ekanem and D A Euba; and by the Electricity Corporation, A A Taiwo

"If this cou se is a success and provides students with the training thep require, we sha l try to arrange further courses for students sponsored by more firms in West Africa and elsewehere,' Dr. C.T. Smith head of the Management Department told our correspondent yesterday.



## British Aircraft Land On Carrier At Sea

PORTSMOUTH—The first vertical landing and take-off from an aircraft carriers by a transonic jet aircraft is achieved as Britain's revolutionary VTOL Hawker P. 1127 is brought down again onto the deck of HMS Ark Royal during tests in the English Channel.

The company's spokesman said that the trials, instituted by Britain's Ministry of Aviation, are most encouraging and demonstate the potetial of this type of aircraft to 'operate from carries at sea.

## Onifaaji Sinku Baba Re

PORTO—Novo ... awọn ọmọ ati ẹbi Ologbe Lamidi Adesian ẹniti o jalusi ninu ile rẹ ni ọjọ Aje ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu ti o kọja ni o pe siba siba si ibi oku alagba na ti nwọn ṣe ni ọjọ keje oṣu yi.

Lemọmu Abudu Raimi ati awọn Alufa Yaya Alhaji Rasaki, Alhaji Ayinde ati Alhaji Biọdun Fagbemi ni nwọn ṣe eto isinku oku na.

Ẹni adọrun ọdun ni baba ti o ku na, o si fi awọn ọmọ mẹtala lọkunrin ati lobinrin saiye ki o to ku, ninu awọn ọmọ rẹ na ni Ọgbẹni L.M. Adesian ('Onifaaji') Sikiru Adesian ati Rasaki Adesian gbogbo wọn ni nwọn si nawo nara nibi oku baba wọn na.

Bẹna si ni awọn ẹbi oku na awọn Ọgbẹni Sadiku Adesian Adeshọkan Adesian, Adelu Adesian, Iyaafin Adetoro Adesian, Adewọnyin Adesian Adebomi Adesian ati Adenilẹ Adesian ti nwọn na wabi wẹsi owo.

## Akowe Ile Owo Gbewa Odun Marun

Ẹjọ ti awọn Ọlọpa ba ọdaran na ro ni iwaju adajọ nipe okunrin kan ti o njẹ Matara Momọdu gbe ponun marun din ni irinwo (£395) lọ si Baki na ati lọ fi pamọ, ọdaran Ogunṣẹyẹ ni akọwe ti o ngba owo lọwọ ẹnia, on na ni o si gba owo lọwọ Momọdu lọjọ na ẹniti o gba owo yi tan, o fun ni iwe-ẹri (passbook) ṣugbọn ko fi owo na jiṣẹ.

Ọdaran na tun gba ponun mọkanlelọgọta (£61) lọwọ akọwe kotu ijọba ibilẹ, Ọgbẹni Julius Ogundare lọjọ ti o wa si Banki lati fi owo pamọ sibẹ, ko fi jiṣẹ. Lọjọ ti gbogbo wọn wa si Banki lati gba diẹ ninu owo wọn ni nwọn to mọ wipe a-pa sinpo ni ọdaran yi ṣe gbogbo owo na.

(O bẹrẹ loju ewe keji)

AWỌN OLE JI KAKI:

## Awọn Kolekole Ji Ade Oba Alakẹ Ko

ABẸOKUTA—Awọn agbalagba ni ole ti o ji kakaki gbe nibo ni yio ti fun un, iyen ni awọn ọlọṣa ti nwọn lọ fọ Afin l'Ake, ti nwọn ji gbogbo ade olowo iyebiye ti Alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji ti o waja laipẹ ti fi owo rẹ, ko lọ patapata.

Onirohin wa ni ọpọlọpọ dukia ti awọn ọba ma nfi ṣẹyẹ ni awọn Ọlọṣa na ji ko lọ eyi ti o dun gbogbo awọn ọmọ, Ẹgba ninu awọn fọ Ọba na ni ADE-GOLU mẹta pataki kan ti nwọn ṣe ni pataki fun "Kabiyesi" nigba aiye rẹ. Bi ode ba di ode pataki ni o ma nlo wọn.

Nwọn ni gbogbo ade-ọba ti awọn ole na ri ko je mọkandinlọgọrun lai ka awọn bata ilẹkẹ ati agborun nla ti Alake Ọba Ademọla Keji nlo nigba aiye rẹ.

Ẹkule agbala ọba ni awọn ọlọṣa na gbe gba wọ ile ṣugbọn awọn otelẹmuyẹn Ọlọpa'nu ti dide si ọrọ na, nwọn si ti nkakiri arọko ati gbogbo ilu agbegbe ti o gbe Abẹokuta bi ilu Ijẹbu mọ Ibadan lati wa awọn ọlọṣa na kiri.

## Alhaja Nimota Laguda Ti Meka De

EKO— Bi a ko lọ a kii de, ni ana Jimọ ni Alhaja Nimọta Nihinlọla Laguda ti Mẹka ti o lọ de si ilu Eko. Tẹlẹtẹlẹ gbogbo awọn ẹbi ni o ti mura silẹ lati lọ pade rẹ ni Ikẹja, sugbọn ojiji ni ọkọ arọpileni ti nwọn wọ gunlẹ ni l'Eko.

Gbara ti awọn Alhaji na ati Alhaja ti gunlẹ ni awọn ẹbi wọn ti ndi mọ awọn ti nwọn ti nda waka ti nwọn nkọrin "OKE ARAFA t'O GUN BARIKA rẹ" fun wọn.

Ẹyẹ na yẹ Alhaja Laguda na pupọ nitoripe gbogbo awọn ẹbi Ojikutu ti wọn wa lọja ni isọ awọn ẹlẹran l'Iko ati Ebute-Mẹtta ni nwọn pejọ si Opopo Egerton ni Oke Arin lati ṣe eyẹ Ẹ KU ABỌ fun Alhaja na, olukulu si nnawo fun ọrẹ ati awọn aladugbo wọn. Ninu awọn ẹbi na ni Oloye Abudu Yẹkinni Ojikutu, Balogni ilu Eko, Lọya Wahabi Ojikutu, Gani Ibikunle Ojikutu, Alhaji S A Bakara, Alhaji Alaka, Alhaja Adijatu Salu, Alhaja Abibatu Kaffo, Iyaafin Suwebatu Ojikjutu ati Tayibatu Alake.



Aso iyawo ti iyekan Oba ilu Oyinbo wo niyi lojo ti nwon gbe e lo si ile oko re, Oruko iyawo ti o wo aso yi ti e nwo ninu aworan yi ni Omo-oba Alexandra, oko re si ni Augus Ogilvy.

# E ka Iwe

**Irohin Ayiluka Ti O Kun Fun Irohin Aladun ni oju ewe Karun.**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370 Editor, (Oloye) Ola Opatade, 15, KosọkọStreet, Box 467 Lagos.